IBADAN. 11/6/77

WEEKS 46&47
Kongi WK 46
17 28 47
Wk 47
9 16 29
Asiko BK WK 46
49 53 54 57
Wk 47
1 17 39 50
Ross Wk 46
53 & 45
WK 47
20&41

Imoḷe Owuro̩

EṢIN ORO̩ WA: IMO̩LE̩ DE OKUNKUN PARADA!

SAMCO OF NIGERIA
WK 46
NAP 2 24 43
Perm 2 24 28 43 58
My Address ?
Not nessesary.
Always meet me in
Imole Owuro
Every Saturday
1 23 24

Independent Paper Vol. XV NO 801. SATURDAY JUNE 11 – FRIDAY JUNE 17, 1977 10K. (KOBO MEWA)

14 JUN 197

# ARA ILU LU O̩GA O̩LO̩PA L'ALUBO̩LE̩ NIBI ORO ṢIṢE

NWO̩N fe̩re̩ gba e̩mi O̩ga O̩lo̩pa kan ni ilu Ahoada ni Ipinle̩ E̩ṣe̩-Odo nitori nwo̩n so̩ pe o di awo̩n lo̩wo̩ nibi oro ti awo̩n nṣe fun enia awo̩n *kan* ti o ku. O̩ga O̩lo̩pa ti nwo̩n digbolu na ni DSP S. K. Igbara.

Irohin fi ye wa pe, oun ti o padi o̩ro̩ na ni pe, nigbati o̩ga O̩lo̩pa Igbara yo̩ju ni e̩hin ile re̩ ni o ri awo̩n o̩po̩lo̩po̩ enia kan ti nwo̩n nko̩rin te̩le o̩kan ninu wo̩n ti o fi agbo̩n ru e̩ru kan, ko̩ja gba e̩hin ile na lo̩.

Irohin fi kun un pe, nigbati o̩ga O̩lo̩pa na ri wo̩n, o ro pe, e̩bo̩ ni nwo̩n ngbe ko̩ja ni e̩hinkunle oun, o si beere lo̩wo̩ wo̩n, idi ti nwo̩n fi nilati maa gbe e̩bo̩ gba e̩hinkule oun lo̩.

Nihin ni a gbo̩ pe, awo̩n enia na ti yari, ti nwo̩n ko kumo̩ ati ohun ija gbogbo, ti nwo̩n si bo ile o̩ga o̩lo̩pa na ṣikan.

Ge̩ge̩ bi irohin ti wi, nihin ni nwo̩n ti be̩re̩ si i le o̩ga o̩lo̩pa na kaakiri inu ile re̩; ati pe, oju re̩ ri mo̩bo ki o to le bo̩ lo̩wo̩ wo̩n ti o si morile ile iṣe̩ wo̩n.

Siwaju si i, irohin so̩ pe nihin ni awo̩n enia na ti be̩re̩ si i ko̩rin ogun

(Woju Ewe Ke̩jo̩)



O̩GAGUN ADEKUNLE LAWAL
Gomina Ipinle̩ Eko

## 'Agbe lu agbe pa nitori ewure'

O̩WO̩ awo̩n O̩lo̩pa ilu Kano ti te̩ awo̩n agbe̩ meje kan fun e̩sun pe nwo̩n lu okunrin agbe̩ miran pa l'ori e̩sun pe o ji ewure̩ elewure̩ gbe; awo̩n O̩lo̩pa si ti ko awo̩n enia na wa siwaju ile e̩jo̩ Magistrate kan nilu na lati koju e̩jo̩ e̩sun ipaniyan.

Awo̩n o̩daran na ni, Garuba Idrisu (52) Abdul Haruna (40) Barau Dawaki (40) Mahamadu Barau (20) Abdul Haruna (22) Umaru Sule (20) ati Musa Idrisu (29) ti gbogbo wo̩n je̩ ara abule Gora ni agbegbe Re̩mo̩ ni Ipinle̩ Kano.

O̩lo̩pa O̩te̩le̩muye̩ kan ti o nka e̩sun si o̩daran na l'o̩run, O̩gbe̩ni Michael Yusufu so̩ fun ile e̩jo̩ na pe, awo̩n o̩daran na, digbolu okunrin agbe̩ kan, Geri Ibrahim, nwo̩n si lu u pa le̩hin ti o̩kan ninu awo̩n o̩daran na, Darau Dawaki ti so̩ pe oun fura si oloogbe na pe o gbe o̩kan ninu awo̩n ewure̩ oun.

Afe̩sunkanni fi kun un pe bi awo̩n o̩daran na ti lu oloogbe na pa

(Woju Ewe Ke̩jo̩)

## Apprentices Wanted

LEARN to become a successful printer; learn on modern machine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern printing, Machine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imo̩le̩ Owuro̩)
N4/496B Yeme̩tu Aladorin,
Ibadan:

## Gomina Eko nfe imototo n'ile ise Ijoba

GOMINA Ologun Ipinle̩ Eko, O̩gagun Adekunle Lawal, ti kesi awo̩n oṣiṣe̩ Ijo̩ba ni Ipinle̩ na lati je̩ ki gbogbo ayika ile iṣe̩ Ijo̩ba maa mo̩ tonitoni.

Laipe̩ yi ni Gomina na pe ipe yi nigbati ti o be̩ awo̩n ile iṣe̩ Igbimo̩ Ijo̩ba Ibile̩ melo kan wo ni ilu Eko ati ayika re̩ ki o ba le mo̩ bawo ni awo̩n oṣiṣe̩ ibe̩ ti nṣe l'e̩nu iṣe̩ wo̩n.

Ninu o̩ro̩ re̩ ni ile iṣe̩ Kansul ayika Eko, Gomina na so̩ pe, ohun ti oun fi oju ri nibe̩ ko dara rara nitoripe, o do̩ti pupo̩ "be̩e̩ si ni, ile l'a ti i ko e̩so̩ rode".

O̩gagun Lawal fi aidun inu re̩ han si iwa awo̩n osṣiṣe̩ kan ti o so̩ pe nwo̩n ki i ṣiṣe̩ wo̩n ge̩ge̩ bi iṣe̩ ati o̩ga ati o̩mo̩ iṣe̩. O ni ara wo̩n ni awo̩n ti nṣe o̩le̩, awo̩n ti ki i wa sibi iṣe̩ deede ati awo̩n ti ko bikita bi iṣe̩ baje̩.

Bakanka ni Gomina na ko ni inu didun si awo̩n oṣiṣe̩ ti o ko̩ lati tun mo̩to ti nkole̩ ṣe ati awo̩n ti o ko̩ lati la go̩ta ti o di. Gomina na kesi gbogbo oṣiṣe̩ labe̩ Ijo̩ba re̩ ti o ba nhu iru iwa bayi lati tete yi iwa pada,



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

"PAṢAN ati ibawi fun ni li ọgbọn ṣugbọn ọmọ ti a ba jọwọ rẹ fun ara rẹ a doju ti iya rẹ," Owe 29 ; 15.

L'oni mo ba gbogbo ẹnyin alabiyamọ ti o wa l'aiye lọkunrin ati l'obinrin yọ, paapaa julọ ti ẹnyin na si tun bimọ. Ogo ni fun Jesu Kristi, Aleluya.

Ṣugbọn mo wa fẹ beere lọwọ rẹ pe, kini iṣẹ rẹ l'ori awọn ọmọ ti o bi ? Bawo ni oruko rẹ ṣe le han l'ara ọmọ rẹ ati pe, iru oruko wo ni o fẹ ki o han l'ara ọmọ rẹ na ?

Awọn ibeere wọn i waiye l'ori oore nla na ti Oluwa ṣe fun ọ nipa pe, O fun ọ l'ọmọ, ati ohun ti iwọ le fi san oore na.

Lati ọjọ pipẹ ninu aiye yi ni oniruuru iwa buburu bi irọ, eke, ole ati bẹẹbẹẹ lọ ti wọpọ laarin ọmọ enia paapaa awọn ọmọde. Bi a ba si nwadi iru awọn ọmọde ti o nhu iru iwa buburu wọnyi, ọpọ julọ ni o jẹ ọmọ ile ɛla tabi ọmọ enia pataki bi olowo, oloro ati onipo nlanla. Itiju gidigidi l'o yẹ ki o jẹ fun iru awọn enia bawọnyi pe, awọn ọmọ wọn ni o pọjulọ ninu ẹni ti nyọ aiye l'ẹnu; awọn ni nwọn maa nhuwa bi ẹni pe ọwọ baba tabi iya wọn ni aiye yi wa.

Bi a ba si nwadi ipilẹ iwa buburu ti awọn ọmọ ti a wi yi nhu, a o ri i pe lati ọdọ awọn obi wọn wa ni. Ngbọ, ki lẹ ti ro pe yio ri, nigba ti baba nfi ibi ti aiye ọmọ rẹ yio pari si bẹrẹ fun un ?

Ani, nigba ti o jẹ pe aṣọ ati bata ti owo rẹ wọn ju l'orilẹ-ede ni o fẹ ki araiye maa ri l'ara ọmọ rẹ nigbagbogbo ! Nigba ti a ba nṣe iru eyi fun ọmọ ti ko ti i mọ bi a ti i ṣiṣẹ owo bawo ni iru ọmọ na ṣe le mọ riri owo ti a fi nṣe nkan wọnyi fun oun ?

## Asipa Oyo nfe Iranlowo Ijoba

AṢIPA ilu Ọyọ, Oloye Afọlabi Okunade Ọlọrunoṣebi ti ke gbajare fun iranlọwọ owo ati ohun elo lati ọdọ Ijọba Ologun Apapọ ilẹ wa ati Ijọba Ipinlẹ Ọyọ lati le ṣe iṣẹ fun un lati ṣe aṣeyọri l'ori iṣẹ odo ẹja ati adagun omi ọlọkẹ mẹwa ti o dawọle l'ọna Ọyọ si Ogbomọṣọ.

L'ọsẹ t'o kọja ni o pe ipe na nigbati o nmu awọn onirohin yika ile iṣẹ na.

Oloye Ọlọrunkoṣebi ṣe alaye fun awọn onirohin pe, bi o tilẹ jẹ pe, iṣẹ ti nlọ gere ge l'ori odo ẹja ati adagun omi naa, o ṣe iṣẹ ki aisi-owo fa ọwọ iṣẹ na sẹhin. O ni o ti to ẹẹdẹgbaasan Naira (N17,000.00) bayi ti oun ti na sori iṣẹna.

Oloye na ran Gomina Ipinlẹ Ọyọ Ọgagun David Jẹmibẹwọn leti ipinnu rẹ ti o ṣe ninu eto isuna rẹ odun ti o koja pe, Ijoba yio maa ṣe atilẹhiu fun awon agbẹ Ipinlẹ yi ti o ba dawole iṣẹ llosiwaju ti o lẹ mu eto oro Aje Ipinlẹ yi lo siwaju ni gbogbo ona.

# Akéde ọ̀nà Ìyè

ỌNAKANṢOṢO SI IYE AINIPẸKUN

## To omo re si ona rere ki oju ma baa ti o (I)

Bawo ni o ṣe le mọ bi o ṣe maa nnira to lati ṣiṣẹ ri owo ? Bawo lo ṣe le mọ pe iya a maa jẹ enia ? Bawo ni ko ṣe ni i maa fi gbogbo owo ti o ba ri ra aṣọ ati bata olowo iyebiye nigba ti o ba dagba tan ? Bawo ni ko ṣe ni i jale tabi yiwe ki o ba le ri owo ra iru nkan wọnyi l'ọjọ iwaju ?

Bakanna, ọpọ obi ni o maa nla oju ara rẹ silẹ ti ọmọ wọn yio fi maa pe ẹgbẹ baba ati ẹgbẹ iya ni nwọn ṣe maa nhuwa aibọwọ fun awọn agba.

Bi oluko ba ba ọmọ wi ni ile iwe, obi miran a mura ija lọ ba oluko. Bi nwọn ba si fi iwa buburu ọmọ rẹ ti o nhu kaakiri han an, ko ni i

### Lati Owo Woli S. I. Owoeye

fẹ gba, nṣe ni yio maa fẹ ki nwọn da ọmọ oun l'are pe, iwa rẹ ti o hu ko buru.

Ewu nla ni iru iwa bayi jẹ fun obi ọmọ ati ọjọ-ọla iru ọmọ bẹẹ nitoripe ọmọ ti a ko ba ba wi, ti obi rẹ ko si tun gba oluko tabi ọga ɹẹ l'aiye lati ba a wi, dajudaju, yio maa gogo si i ninu iwa buburu; nigba ti o ba si ya ti iwa buburu na ba nso eso; eso ibanujẹ ni yio so, obi rẹ yio jẹ nibẹ, inu rẹ yio si bajẹ, bẹẹ ni ọmọ na tikalararẹ ni yio si jẹ gbogbo ere iwa buburu rẹ; itiju a si ba oruko obi rẹ.

Ẹ jẹ ki ọrọ yi jẹ ẹkọ gidigidi fun ẹnyin obi gbogbo. Ọrọ ọmọ rẹdi ọwọ rẹ paapaa ẹnyin ti ẹ fi ọmọ nyin silẹ lai kọ ti ẹ nkọlemọle, ẹ ko mọ pe, ọmọ ti enia ko ba kọ ni yio gbe ile ti o ba kọ ta ?

Awọn obi miran ẹwẹ a maa sọ pe, awọn ko fẹ ki ọmọ awọn tun jẹ iru iya ti awọn ti jẹ ninu aiye, nitorina, nwọn a fi ọmọ wọn silẹ lai fi ẹkọ aiye kọ ọ, nwọn a si maa kẹ ẹni oju, kẹ ẹ n'imu. Njẹ ẹnikẹni ha le fi opin si iya jijẹ fun ọmọ rẹ ? Tabi, iru ile ẹkọ wo ni ọmọ ti a ki i ba wi yio lọ ti o le mu oruko rere wale ?

Nitorina iwọ ọmọ enia, Ọlọrun npe ọ l'oni pe, bi iwọ ko ba fẹ ki iya jẹ ọmọ rẹ, tọ ọmọ rẹ ni ọna ti o tọ. Jẹ ki ọmọ rẹ mọ iyatọ ninu ibi ati rere toripe Oluwa l'O da mejeeji.

Bakanna ni mo si npe ọkunrin ati obinrin nibi gbogbo pe, ki ẹ ronu ibi ti iṣina nyin ti maa nwa ki ẹ le mọ ibi ti ẹ o doju adura nyin kọ ti ẹ o si ti ṣe atunṣe, ati ọna ti ijiya ti maa nwa fun ọmọ nyin.

Tabi iwọ ti o lọ gba iyawo ẹgbọn rẹ; iru ọmọ wo l'o ro pe ẹ le bi ti yio huwa otitọ ? Iwọ ti o fi ogungun pa ọkọ ti o wa sọ iyawo rẹ di tirẹ, iru ọmọ wo ni ẹ ro pe e fẹ bi ? Bibeli wi pe, "Igi buburu ko le so eso rere bẹẹ ni igi rere ko le so eso buburu."

Nitorina ẹnyin obi gbogbo l'agbaiye, ẹ jẹ ki a pe apero lati gba iwa buburu silẹ lọwọ awọn ọmọ wa. Ẹ jẹ ki a jẹ apẹẹrẹ rere laarin wọn ki nwọn le kẹkọ ohun rere lọdọ wa k'a to ki aiye pe, "o digba – ọsẹ".

L'oruko Jesu ti o ba di ọsẹ ti o nbọ, ẹ o gbọ nipa baba kan ti itan sọ fun wa pe o ṣi ọmọ rẹ tọ ti nwọn si jere itiju.

## IWE ỌRỌ ỌLỌRUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkookan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa, Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÌGBÈSÌ...

## IPADE (59)

Adeyẹmọ Ọjẹrinde
AGO onile, onile mo k'ago o.
Ayinde nbẹ nile ni
Tabi ko si nile?
Lawuyi Ogunniran
Ọmọ Ajişegiri:
Maa wole, maa rọra.
Ayinde nbẹ nile
Ng ko kuku r'ajo.
Iyawo rẹ nkọ?
Şe nbẹ lalaafia ara?
Gbogbo ọmọ nyin nkọ?
Ara le tabi ko le?
Ajao Alayọ ọmọ Irioşeje?
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
O şehun l'aiye ọmọ Ejigbọjọ
O ku ifẹ mi
Odumare ko ni i jẹ ki
Ohun t'o nro ja bụẹbuẹ.
Dakun, Ayinde,
Ma binu pe ng ko tete de.
Aitete r'ọna rin ni
Ko jẹ ki ng kanju de.
Wayi o, ọmọ Ejigbọjọ,
Aaye aroye ko si l'oni,
Jẹ k'a maa ba faaji wa lọ.
Lawuyi Ogunniran
O ti ya, ọmọ Ajişegiri
Jẹ k'a tete kia,
K'a ma f'akoko şofo.
Maa pajuba nişo
Ki ng kọbe lẹyin rẹ
Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Bawo ni o şe sọ pe
Ki ng maa pajuba nişo?
Şebi, iwọ l'o şe 'leri
Pe, o o maa ba ọrọ lọ
L'ori awọn alakọwe asiko
T'o sọ pe ko si oşo
T'o sọ pe ko si ajẹ,
T'o sọ pe ko s'emere,
T'o sọ pe ko s'oloogun ika?
Ayinde ọmọ Ejigbọjọ,
Ma jẹ k'a doju eto yi ru
Ma jẹ k'a lo ayinnike,
Nşe ni ki o maa sọ fun wa.
Lawuyi Ogunniran
Ootọ ni, bẹẹ na ni
Irọ kọ l'o pa.
Ki i şe pe, mo ndoju eto ru,
Ki i şe pe, ng ko fẹ sọrọ;
Tabi o ko mọ pe,
Ọmọ ale eniyan nii sọrọ
Ti ki i se bẹẹ mọ
Jẹ ki ori rẹ maa pe
Bi o ba nran mi leti ọrọ
Ti mo ba gbagbe,
Ma şe yanu sọrọ s'iru awa.
Mo fẹ ki o lọ joko jẹẹ
Nitori garaje rẹ pọju
Wayi o ibi a roko ti si ni
Aa f'abọ si b'oju ba mọ
Ibi ti mo deduro ni pe
Alakọwe ko mọ ẹwẹ rara
Bẹẹ ni nwọn ko mọ owe;
Alakọwe ko mọ oogun
Nwọn npe e l'ẹfọ;
Alakọwe ko mọ aiye
Bi o ti ri wọn nibigbogbo.
Idi niyi t'o fi yẹ
K'a jswe ẹwẹ s'ọwọ ọtun,
K'a jawe owe s'ọwọ osi;
K'a wa pe alakọwe ki o wa,
B'o ba de tan,
K'a f'ewe ẹwẹ le e lọwọ ọtun,
K'a f'ewe owe le e lọwọ osi,
Ki nwọn baa le mọ
Iyatọ laarin wọn,
Ki nwọn ma baa maa fi
Ewe ẹwẹ pe owe,
Ki nwọn ma baa se ẹwẹ jẹ.
Ki nwọn jẹ e tan
K'o maa waa yọ wọn l'enu.
Nitori owe l'a a yilẹgusi
Ti a fi i jiyan ẹgbodo
Nitorina, ọmọ Ajişegiri,
Ati ẹnyin onkawe
Paapaa alakọwe asiko;
E jẹ k'o ye nyin gidi
Pe, oşo nbẹ, ajẹ nbẹ,
Emere nbẹ,
Oloogen ika nbẹ,
Gbogbo wọn l'o nbẹ l'aiye,
Gbogbo wọn ni nbẹ l'aaye
Ajao! Maa gbọ ọmọ Ajişegiri,
Ọpọ alakọwe ni njiya
Nitori ainigbagbọ
L'ori ọrọ yẹn gbogbo,
Ọpọ l'o si jẹ alagabagebe.
B'o ba di oju eniyan
Yoo sọ pe ajẹ ko si,
B'o ba de kọlọfin
A maa rubọ si wọn!
B'ọmọ eniyan şe ri ree,
Ti nwọn i tan 'mọ s'ija ẹkun.
O ni ko si oşo,
O nrubọ fun oşo!
O ni ko s'ajẹ
O nşe ẹbẹ awọn agba;
O ni ko s'oogun ika,
O nşe madarikan kiri!
O ni ko s'emere
O nrubọ f'ẹgbẹ atọgba!
Şugbọn o nsọ f'ẹlomii
Pe, ko ma bikita kankan;
A ni k'o ma şe bẹru fun
Ohun ti ko si ni duniyan.
Iwa agabagebe eniyan ree o
Baba Kafilatu!
O ko r'eeyan bi ọmọ Ajişegiri?
Ọtọ l'ero inu wọn,
Ọtọ l'eyi ti nwọn nwi!
Bẹẹ l'ọpọ alakọwe nhuwa
Ti nwọn nti ọpọ miran
Sinu iyọnu gbogbo!
Idi si niyi ti o fi ri
Ọpọ ọmọwe ti ko l'apọnle ẹda,
Ti ko n'ibẹru eeyan!
Ti ko bẹru oşo
Ti ko bẹru ajẹ,
Ti ko bẹru emere,
Ti ko bẹru oloogun ika,
Ti ko bẹru eşu,
Ti ko bẹru Ọlọrun
Nitori nwọn sọ pe,
Ko si 'hun ti i jẹ bẹẹ nibikan.
Ajao! Jẹ k'a duro nihin
Nitori akoko nbuşe,
B'o ba d'Ipade taa bọ si
K'a maa ba 'yoku bọ.

Rajest Tip

**15**
**28**
**46**

IWE IGBAẸLODE
DARA PUPỌ,
RA TIRẸ NIBẸ
1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba ₦10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (₦1)
5. Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaşoro (₦1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦6); Kekere (50k)
9. Iwe ala ni nla (₦2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)
FI OWO ATI STAMP (5k) RANŞẸ SI:
(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeoyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.

(2) Alufa Igbaẹlode, Mọşalaşi Idi Işin St. Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin

**Ẹgbọ t'emi**

# Olowu wo ni ade ye fun ?

OLOOTU,

MO ri i ka ninu iwe irohin Imọlẹ Owurọ laipe yi pe, Ijọba Ipinlẹ Ọyọ ti fi aṣẹ si i pe ki Ọba mẹtadinlaadọrin maa de ade onilẹkẹ, ṣugbọn ki a to pin Ipinlẹ titun, gbogbo Ọba ilẹ Yoruba jẹ mẹrindinlogun.

Awọn ọba na ni, Ọọni Ifẹ, Alaafin Ọyọ, Ọwa Ilẹṣa, Alake Abẹokuta, Awujaalẹ Ijẹbu, Ajero Ijero, Alara Ara, Osemawe Ondo, Onibinni Ibinni, Ọrangun Ila, Olowu Owu, Ewi Ado-Ekiti, Alaketu Ketu, Ẹlẹkọle Ikọle ati Onisabẹ Sabẹ.

Diẹ ninu awọn Ọba ti o a darukọ wọnyi ti bọ si Ipinlẹ Ondo ati Ogun ṣugbọn ninu awọn ti o ndade ni ilẹ wa ni Onisabẹ wa, a ko si ri orukọ rẹ nibẹ.

Ati pe, Olowu – Owu wa lara Ọba alade tẹlẹ ṣugbọn mo tun ri i ka ninu irohin nyin na pe, Olowu Owu – Ẹpẹ ati Olowu-Owu Ejigbo tun wa nibẹ. Ẹ jọwọ, ewo ni i ṣe nibẹ tabi Olowu Orile – Owu ni ?

Emi ni,

Wahabi Any-news,
Ibadan.

AKIYESI

Ọrẹ wa Wahabi, ni ọna kinni, ki iṣe ọba alade mẹrindinlogun pere ni o wa ni ilẹ Yoruba tẹlẹ lati ipilẹ wa, ba ọalade pọ jaburata.

Ni ọna keji, awọn miran wa ti ko kọwe si Ijọba pe awọn fẹ maa de ade babanla awọn.

Ni ọna kẹta, gbogbo ibi ti a ba ri ilu Owu ni o lẹtọ lati de ade nitoripe Olowu igba kan tabi ọmọ Ọba Owu ni o tẹ awọn ilu Owu do.

Ki iṣe Ipinlẹ Ọyọ nikan ni Owu wa. Owu wa ni Ogun o si tun wa ni Kwara. Ni Ipinlẹ Ọyọ yi, Owu tun nbẹ ni eti Ifẹ-Ọdan pẹlu. Nitorina, gbogbo ibi ti a tẹjade nni titi de Orile-Owu ni yio maa dede.

—OLOOTU

# Ki l'o se ti Akirun ko dade?

OLOOTU,

NINU Imọlẹ Owurọ ni mo ti ka a laipẹ yi pe, Ijoba Ipinlẹ Ọyo fi aṣẹ si i pe ki oba mẹtadinlaadorin maa de ade onilẹkẹ.

Bi o tilẹ jẹ pe agbegbe Ọṣun ni awon Ọba na poju si gẹgẹ bi ẹ ti wi, mo wo oruko gbogbo won ṣugbon o ya mi l'ẹnu pe ng ko ri oruko Ọba wa, Akirnn Ikirun nibẹ.

Ki l'o fa a ti o fi ri bẹẹ. Olootu ! ko ye mi l'o jẹ ki ng beere bẹẹ o.

Emi ni,

Y. Bolarinwa,
Ibadan.

AKIYESI

Ọrẹ wa Bolarinwa, ayẹwo finnifinni nipa itan iṣẹdalẹ awon ilu wonyi ni Ijoba tẹle lati paṣẹ na.

— OLOOTU

## Ofin na dara

OLOOTU

GBA mi l'aye lati kan saara gidi si Ijoba Ologun Apapo labẹ Ọgagun Agba Oluṣẹgun Ọbasanjo fun atunṣe ti nwon tete maa nṣe si ohun yowu ti o ba npon mẹkunnu loju.

Inu mi dun pupo nigba ti mo ri i ka pe Ijoba Apapo ti tun ofin afipajale ṣe ati ti onifaiyawo nipa eyi ti nwon yio fi le tete maa paa adigunjale yowu ti o ba jẹbi ti nwon o maa ju onifaiyawo sẹwon odun marun nigbati eyi ti o ba pa oṣiṣẹ onibode l'ara yio si kẹhin si agba.

Iru Ijoba rere ti yio maa mojuto alaafia awon enia Orilẹ – ede bayi ni awa nfẹ ni ilẹ wa.

Oluwa yio ti nyin lẹhin o, Aamin.

Emi ni,

Julius Iyiola,
Iṣẹyin.

**!2**

KEREO
GBOGBO - ENIA!
fun
Ipolowo oja ati Ikede,
Akiyesi ati Itufọ,
Iranti oku ati Ikede Ariya,
Ikilọ ati bebẹ lọ;
Tabi Almanak ati Kalẹnda tite.
DARAPỌ PẸLU AWỌN ỌLỌGBỌN ENIA TI O NSEE SI INU (IMỌLẸ OWURỌ) TI O GBAJUMỌ KARI AIYE. OWO TI A NGBA KOPO.SA KỌWE TABI KI O WA RI :-
Advertisement Manager:
IMOLE OWURO
N4/496# YEMETU ALADORIN.
P.M.B. 5230, IBADAN.

NIGERIA NEW STATES CO.
NNSC
Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹ lo, Ile Iṣẹ wa wa ni:
18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.

Gbemisola Nap

**2 8 30**

# Omo baba marun ku sinu kanga

IROHIN lati ilu Sokoto ni Oke-Ọya fi ye wa pe, ajalu buruku ti jalu idile kan nigba ti ọmọ baba marun ku sinu kanga lẹsẹkẹsẹ. Ni adugbo Rungumi ni ilu Sokoto ni o ti ṣẹlẹ laipẹ yi.

Irohin fi ye wa pe awọn ọmọ baba maraarun na to ẹni ọdun mẹtalelogun si mejidinlọgbọn.

Gẹgẹ bi irohin ti a gbọ lati ẹnu ọga panapana ilu na, Malam Alhassan Bida ti wi, ọkan ninu awọn ọmọ na lo ja si kanga.

O ni, bi eyi ti ṣẹlẹ ni ọkan ninu awọn mẹrin yoku bọ tọ ọ ninu kanga na lati yọ ọ.

O ni nigba ti ko ṣe e ṣe, omiran tun bọ tọ awọn meji tihin, ati pe bẹẹ gẹgẹ ni awọn maraarun ṣe ku sinu kanga na.

Ọga panapana na sọ pe nigba ti awọn aladugbo pe awọn de ibi kanga na ti awọn yẹ inu rẹ wo, awọn ri i pe, ooru burukuburuku ti o nti inu kanga na jade wa le pa enia laarin iṣẹju marun pere.

O ni nihin ni awọn ti pe awọn onisẹ olomi lati fi ẹrọ wọn fẹ atẹgun sinu rẹ ki awọn to le wọnu kanga na lọ ti awọn si ko oku awọn maraarun jade.

Bayi, awọn Ọlọpa nṣe iwadi lọwọ l'ori iṣẹlẹ na.


## IKEDE PATAKI

A nfẹ awọn oṣiṣẹ wọnyi kiakia ni ibikibi lati Ipinlẹ Ọyọ:

(a) Ọgọrun (100) Birikila.
(b) Aadọta (50) Amọ-bulọọku (Block-makers)

Iṣẹ gbigba:

Aaye wa fun awọn Birikila ti nọwn ba fẹ da iṣẹ gba.

Owo mọto:

A o fun awọn ti nwọn ba ni, ti nwọn si ṣetan lati gbe ẹrọ imọ-bulọọku ati Palẹti wa ni owo mọto ṣugbọn iru enia bẹẹ yio kọkọ ri wa na. ₦50.00 ni a nsan fun ẹgbẹrun bulọọku (1000-blocks) ni agbegbe (outside town). Naira meji lojoojumọ ni a nsan fun ẹrọ kan.

Owo sisan:

Ọsọọsẹ ni a nsanwo fun awọn oṣiṣẹ wa, ayafi awọn ti nwọn ba fẹ tiwọn l'oṣooṣu.

Ki ẹ tete wa ri:

Oloye Victor Lajide
Ati
Mr Ajibade Lawal

Awọn Oludari:-

VICTORY BUILDER & AGENCIES,
Lajide Compound,
Ọyọ Road,
P. O. Box 44.
Ogbomọṣọ.


## Ogunranti Nap

**14 17 20**
**25 34 48**

# Egbe Imole Owuro

12,519 David O. Julius Ado-Odo
12,520 Sunday Fakunle, Ogbomọṣọ.
12,521 Abiọdun Ọlalẹyẹ, Ilesa
12,522 Abraham Bamidele, Ilora
12,523 J. Rotimi, Ọke-Agbe
12,524 Baṣiru Ogundapo, Ibadan
12,525 Ambali Adeniran, Iwo
12,526 Jimo A. Yusuff, Iludun-Oro
12,527 Tijani Adegoke Eko-Ende
12,528 Emman Ọmọlafẹ, Akurẹ
12,529 Ṣangoloni Ọladokun Ado-awaye
12,530 G. Bamidele Akins, Ibadan
12,531 Rasaki Alabi, Ilọrin
12,532 Alhaji Belo Alagbala, Ilorin

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA
DI

## Omo Egbe Imole Owuro

Iwe Idi Ọmo Ẹgbẹ)

Oruko rẹ.............................................

Adirẹsi rẹ.............................................

Ọmọ Ilu ti o jẹ.............................................

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akọwe Ẹgbẹ)
P.M.B. 5230, Ibadan.


# Aiyedetisola Commercial Electrical Store:

**Will satisfy all your electronics needs at reasonable prices**

**Call at**

N27&41A I.C.C STALL
AGODI GATE
IBADAN

## Agbéyẹ̀wò ohun titun t'o gbòde

REKODU, IWE, ORIN, ARE-IDARAYA

# Alhaji Odolaiye Aremu tun de s'oju Opon Orin

ẸNI t'a nwi, o de
Odolaiye Arẹmu o de!
Akọrin-bi-ẹni-ndifa, o de
Apede-bi-ẹni-nşanpẹlẹ, o de
Baba ni Kwara — o de.

Gbogbo eniyan l'o m'ẹkun, enia melo waa ni ẹkun yio mọ? Gbogbo ọmọ Yoruba l'o mọ Odolaye Arẹmu gẹgebi Ọga pataki ninu Ọlorin Ilọrin, şugbọn eniyan melo ni Odolaye fun ara rẹ mọ ?

Odolaye ti şe awo orin fẹrẹ to ogoji ni Naijiria. Lasiko igba ti ina orin rẹ si njo bula-bula, takọtabo l'o maa nra a witiwiti. Eyi ti o ta julọ ninu awo orin Odolaye ni nkan bi ogun ọdun sẹhin, ko si ẹni to lee tete gbagbe rẹ. Orin naa ni:

"Eegun Alare — Ọmọmọşẹ
Ng o kan ọ l'abuku — Iwọ naa paa ntokọẹtẹ bọ
Amala-nsọrọ-Ọbẹyọ — eebo
I am Coming — Eebo ati bẹebẹẹ lọ

Ile ẹkọ ni mo wa nigba naa, igbakugba ti ẹnikan ba si ti fọ eebo, Kandukandu, gbogbo wa l'a maa mpariwo "eebo", ni iranti awo Odolaye.

Şugbọn l'ojiji ni a ko gburo Odolaye mọ lati bi ọdun mejila sẹhin. O ti waa de o, o ti gbe ara miran de.

Ninu awo orin tuntun yii, Odolaye fi orin Ilọrin pẹlu ilu aramọnda t'o gbamuşe şe idaro awọn akọni nlanla ni Naijiria. Awọn eniyan bi Ọgagun Muritala Mohamed, Ọgagun Taiwo, Alhaji Adegoke Adelabu, Pẹnkẹlẹmẹsi, SLA Akintọla Premier Western Region.

Bi Odolaye ti şe nki "Belo" t'o ku, bẹẹ l'o şe nki "Belo" ti koi ku, bo ti şe njuba ara aiye, bẹẹ l'o njuba ero ọrun. K'oşeemani ni awo orin yi i nitoripe ede Ijinlẹ Yoruba gidi ni.

A tilẹ gbo wipe, l'oşu mejimeji ni awo ODOLAYE fẹ maa jade bayii, lati ile işẹ Rekoodu Ọlatunbọsun, t'o wa ni Odikeji Agodi Testing Ground, Iwo Road Ibadan. Naira marun nigbogbo awo Rẹkọọdu n'ile işẹ yi i, wọn si nta a ni edinwo paraku fun awọn ti o ba ra pupọ. Nọnba awo na ni : ORCLP21. Awọn ẹni ti o tun kọrin le lori ni oloogbe Kadiri Oba Ilọrin, Ọba Ilọrin ti o wa l'ori oye bayi, Oba Sulu Gambari, Awọn pataki alade Ọyọ, Dokita Saraki, Turaki Ilọrin, Laaro Balogun ati Tapa Lempe.

Nwon ti bẹrẹ si i du awo Odolaye na ra bayi, tete lo ra tirẹ tabi ki o wadi nile işẹ :
Ọlatubọsun Records Company,
P. O. Box 1113, Agodi, Ibadan.



ALHAJI ODOLAIYE ARẸMU
(Gbajumo Alare Dadakuada)

# Ara ilu lu Oga Olopa

(Lati Oju Ewe Kinni) ti nwọn si bẹrẹ si i le e lọ si ile iṣẹ wọn ti o salọ.

Irohin fi ye wa pe, nihin ni ijakadi ti o galọla ti ṣelẹ nitoripe awọn enia na taku pe awọn yio jẹ Ọga Ọlọpa na niya dandan ni, ki awọn Ọlọpa yoku ti i sita. Ṣugbọn awọn Ọlọpa tihin sọ pe ko s'aye.

Nihin ni ija ti burẹkẹ nigba ti awọn enia na sọ pe, Ọga Ọlọpa na ti ba oro ti awọn nṣe fun enia awọn ti o ku jẹ nitorina, o nilati f'ori fa a, nwọn si nfẹ fi girimọkai wọ ile iṣẹ Ọlọpa na lati mu Ọga na. Awọn Ọlọpa kọjalẹ lati jẹ ki nwọn wọle, ni ija ba sọ.

Irohin fi ye wa pe, ọpọlọpọ wakati ni ija na fi waiye, ti tọtuntosi si nja raburabu.

A gbọ pe ọpọlọpọ enia l'o farapa ninu ija na ṣugbọn ọwọ awọn ara ilu ko tẹ ọga Ọlọpa na ti nwọn nwa.

Irohin fi ye wa pe, enia mẹta ti ọwọ awọn Ọlọpa tẹ wa ni ẹsẹ kan aiye ẹsẹ kan ọrun bayi ni ile iwosan Elete ni ilu Ahoada.

Bayi, irohin lati ilu na fi ye wa pe, awọn

agbaagba ilu na, tọbatijoye ati awọn Ọga Ọlọpa ti bẹrẹ si i ṣe ipade ipari ija laarin tọtuntosi na.

Ninu ọrọ rẹ nibi ipade ija na, Ọga Ọlọpa fun agbegbe na, Oloye A. O. Ṣọlagbade sọ pe iṣẹ awọn Ọlọpa ni lati wa alaafia ati lati daabo bo ẹmi ati dukia ara ilu.

O rọ wọn lati fọwọwọnu ki nwọn si maa fọwọsowọpọ pẹlu awọn Ọlọpa fun alaafia ilu. Ara awọn enia ti o wa ninu ipade na ni Oloye N. T. Imo ati Ọgbẹni C. E. Ideozu ti iṣe Kansilọ kan ni ilu na.

# Ole agbewure

(Lati Oju Ewe Keje) S. O. Kọlade sọ pe, oun da awon enia na lẹbi, o si paṣẹ pe, ki nwon lọ fi ẹwọn jura.

Bakanna ni Adajọ paṣẹ pe ki mọto Pick-up 404 ti nonba rẹ jẹ WE 4698 A ti nwon fi ko ewurẹ na di ogun ajẹmonu fun Ijoba Ipinlẹ Ọyọ.

# Agbe lu agbe pa nitori ewure

(Lati Oju Ewe Kinni) tan ni wnọn ti digbolu awọn ẹbi oloogbe na ti nwọn si ṣe wọn bi ọṣẹ ṣoju. Ninu idigbolu na gẹgẹ bi afẹsunkanni ti wi, awọn ọdaran na ji ẹgbẹrun Naira (₦1000.-00) ati ọpọ dukia ninu ile oloogbe na.

Nwọn ni ọkunrin kan ni abule na, Ọgbẹni Nayaya Gari ni o fi ọrọ na to awọn Ọl pa leti ki o to di pe, awọn ọlọpa ko awọn ọdaran na ninu ile oloogbe na.

Nwọn ko ti i gbọ ti ẹnu awọn ọdaran na ṣugbọn Adajọ ile ẹjọ na, Malam Tijani Abubakar paṣẹ pe ki nwọn lọ ti awọn ọdaran na mọ ọgba ẹwọn titi di ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu keje ọdun yi.

# 2 3 16
# 30 7 8


# OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD

TI TUN GBE ORIRE DE.
A TI GBE TANA DANU
A TUN GBE OMIRAN DE
A TI NI ẸRỌ ATATA YI:



## Cassava Grater

(WITH JLO L101 ENGINE) **(₦350.00)**

(EYI NI ẸRỌ TI NWỌN FI NRIN GARI OLOWONYỌ)

Aiye ti di jẹlẹnkẹ,
Ko si ki a maa fi agbara wa owo mọ.
Bi o ba ti ni ero yi kanṣoṣo
Jẹ ki okan rẹ balẹ pẹsẹ
Nitoripe owo-nlanla
Ni iwo yio maa pa.
Owo ero na ko po rara
₦350.00 pere ni.
Ẹ maa bọ taara si:

## Western Nigerian Technical Company Limited

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.


Printed and published by the People's Star Press Limited, N4/4903 Yemetu Aladorin P. M. B. 5233, Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran, E4/803, Aparin Adekile Ibadan. Lagos Office 18, Odunlami St, Phone 27017.